# SISẸ̀ JESU ATI IDAJỌ ÈKÉ TI A ṢE FUN UN

### Matteu 26:47-68; 27:1, 2, 11-26

### ẸKỌ 431 -- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "A kẹgan rẹ̀ a si kọ̀ ọ lọdọ awọn enia, ẹni-ikãnu, ti o si mọ̀ ibanujẹ" (Isaiah 53:3).**

**A Mú Jesu bi Ondè**

Kristi ti bori ogun ti ẹmi lori eekun Rẹ̀ ninu adura Rẹ̀ si Baba, iru adura ninu eyi ti oogun ti n jade ni ara Rẹ̀ dabi iro ẹjẹ nla. Ṣugbọn nisisiyii O dide, O si rọra bá awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ lọ lati pade awọn ọta. O wi fun awọn ọmọ-ẹyin rẹ̀ pe ẹni ti yoo fi Oun hàn wa ni tosi; ki O to pari ọrọ sisọ, ọpọ awọn ọmọ-ogun Romu ati awọn akowe oniwa buburu ati awọn Farisi dé, pẹlu idà ati ọgọ ni ọwọ wọn. Judasi ti i ṣe olori agbajọ awọn eniyan-keniyan wọnyii wá siwaju lati fi ẹnu ko Jesu ni ẹnu. A le maa ro pe o yẹ ki oju ti Judasi lati hu iru iwa ojo bayii to bẹẹ ti oun ki yoo fẹ ki ọ̀kan ninu awọn ọmọ-ẹyin ri oun, ṣugbọn eyi jẹ apa kan adehun ti o ti bá awọn olori alufaa ṣe.

Jesu ti jẹ oninuure ati oniwa-pẹlẹ laaarin awọn eniyan naa nigba gbogbo. O ti n kiri, O si n ṣe rere. Ṣugbọn nisisiyii awọn ọta Rẹ̀ wá loru ninu okunkun lati mu Un gẹgẹ bi onde, gẹgẹ bi ẹni pe arufin ni Oun i ṣe. Jesu ko jà rara; ṣugbọn iṣoro kan wa ninu ati mu Un. Nigba kan awọn olori alufaa ti rán awọn eniyan lati lọ mu Jesu, nigba ti wọn pada de lai le mu Jesu pada pẹlu wọn, ohun kan ṣoṣo ti wọn tẹnumọ ni pe, "Kò si ẹniti o ti isọ̀rọ bi ọkunrin yi ri" (Johannu 7:46). Awọn ọrọ ti o ti ẹnu Rẹ̀ jade ni o lé awọn wọnni ti wọn fẹ mu Un pada. Nisisiyii paapaa ninu ọgba nibi ti ọpọ awọn eniyan buburu wà, wọn bi sẹyin wọn si ṣubu lulẹ nigba ti Jesu wi fun wọn pe Oun ni ẹni naa gan an ti wọn n wá. Oun ta eniyan ẹlẹran-ara yọ: Ọmọ Ọlọrun ni Oun i ṣe, Oun si ni gbogbo agbara ni Ọrun ati ni aye, O si le lo o bi O ba fẹ ṣe bẹẹ. Kò yẹ ki O gba awọn eniyan buburu wọnyii láàye lati de Oun. Ọlọrun le rán legioni angẹli mejila (bi iwọn ọkẹ mẹta o le ẹgbaarun (70,000) angẹli tabi ju bẹẹ lọ) ninu eyi ti ọkọọkan wọn le pa gbogbo ọta Kristi run nipa ifi ọwọ kan wọn lasan. Ṣugbọn eyi ki i ṣe ifẹ Ọlọrun. Wakati Olugbala ti de ti a o pa A gẹgẹ bi Ọdọ-agutan Etutu.

**Ailagbara Eniyan lai si Ọlọrun**

Fi awọn angẹli ti Jesu i ba pe sọkalẹ wé ida kekere ti Peteru ni lọwọ rẹ̀. Gbogbo agbara ti Peteru le sà ni lati ké eti ọmọ-ọdọ kan kuro. Bi ailagbara wa ti to ni yii nigba ti a ba fi wé agbara Ọlọrun wa. Ṣugbọn bi o ba jẹ ifẹ Ọlọrun ni fun awọn ọmọ-ẹyin lati gbeja Oluwa wọn, ẹni kan ṣoṣo ninu wọn i ba ṣe nnkan nla. "Bi Ọlọrun bá wà fun wa, tani yio kọ oju ija si wa?" (Romu 8:31); ati "Ọkunrin kan ninu nyin yio lé ẹgbẹrun: nitoripe OLUWA Ọlọrun nyin, on li ẹniti njà fun nyin" (Joṣua 23:10). Ogunlọgọ awọn ọmọ-ogun pẹlu ida ati ọpa wọn i ba di alailagbara bi o ba ṣe pe ifẹ Ọlọrun ni pe ki Kristi sá asala.

Jesu gbà fun awọn ọmọ-ogun lati mu Un lọ si gbọngan idajọ; gbogbo awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ si fi I silẹ. Jesu, Ẹni ti O rú ẹbọ ti o tobi ju lọ -- O fi ẹmi Rẹ̀ lelẹ fun awọn ọta Rẹ̀ -- O dabi ẹni ti kò ni ọrẹ kan rara ni wakati ti O wà ninu iṣoro Rẹ̀ ti o tobi ju lọ. Awa ko ha fẹran Olugbala nitori igbese ti O san?

**Awọn Ẹlẹri Eke**

Lakọkọ a mú Jesu lọ si ile Olori alufaa. A pe awọn ẹlẹri lati jẹri eke si Jesu, ṣugbọn a kò ri ẹni kan, nitori pe Oun kò ṣe buburu kan ri. Nikẹyin awọn ẹlẹri eke meji dide, ṣugbọn ọ̀rọ awọn mejeeji kò ṣọkan lori irọ́ ti wọn pa. Kò tilẹ yẹ ki a gba ẹri wọn rara, ṣugbọn nitori awọn Ju wà ninu ibinu nla, wọn ṣe bi ẹni pe ohun ti wọn sọ tọna. Ọ̀kan ninu awọn ẹlẹri naa sọ ninu ọrọ rẹ̀ pe Jesu wi pe, "Emi ó wó tẹmpili yi ti a fi ọwọ́ ṣe, niwọn ọjọ mẹta emi o si kọ́ omiran ti a kò fi ọwọ́ ṣe." (Marku 14:58). Ṣugbọn ki i ṣe ohun ti Jesu sọ ni yii. Awọn ọrọ Rẹ̀ ni yii: "Ẹ wó tẹmpili yi palẹ̀, ni ijọ mẹta Emi o si gbé e ró." (Johannu 2:19). O n sọrọ nipa ara Oun tikara Rẹ̀, pe ẹlomiran yoo wó ara Oun palẹ, ṣugbọn Oun yoo tikara Oun tun gbé e dide. Oun ko sọ ohunkohun nipa ile rara.

Lẹyin naa, Olori Alufaa ni ki Jesu jẹri gbe ara Rẹ̀. Eyi pẹlu lodi si ofin awọn Sanhedrin, eyi ti i ṣe Igbimọ ti n ṣe akoso awọn Ju. Bi eniyan ba tilẹ jẹwọ paapaa pe oun jẹbi, a ki yoo gba ẹri ti o jẹ́ gbe ara rẹ̀. Lori ẹri otitọ ti ẹlẹri meji miiran ba jẹ́, ti o si bá ara wọn mu ni a le fi dá eniyan ni ẹbi.

Awọn eniyan naa tutọ si Jesu loju; wọn kan An lẹṣẹ; wọn si fi ohun bu ẹtẹ nla lu U. Gbogbo nnkan wọnyii ni o lodi si ofin awọn Ju. Olukuluku onde ni a gbà si alaiṣẹ̀ titi di akoko ti a ba ṣe iwadii ọran rẹ̀ ti a si fi idi rẹ̀ mulẹ pe o jẹbi; ṣugbọn ibinu awọn eniyan wọnyii mu wọn gbagbe gbogbo ofin ti n ṣe akoso iwa wọn.

Idahun Kristi bi alufaa ninu tobẹẹ ti o tikara rẹ̀ fa aṣọ rẹ̀ ya, o si wi pe o yẹ ki Jesu kú. Ni otitọ, awọn Ju ti fi imọ ṣọkan lori eyi ṣiwaju ibẹrẹ iwadii ọran Jesu. Iwadii ọran ti a ṣe jẹ́ aṣehàn lati tẹ́ awọn wọnni lọrun ti o le beere lọwọ wọn eredi rẹ̀ ti a fi pa Á ni kiakia.

**Peteru Sẹ́ Jesu**

Nibo ni Peteru wà nigba ti Olugbala n fi ara da irẹsilẹ yii? O ti n tọ Jesu lẹyin ni okeere lati ri ohun ti yoo ṣẹlẹ, o si wà ni ipo ti o lewu pupọ. Lakọkọ, o ti kuna lati ṣọna ati lati gbadura, lẹyin naa o n tọ Jesu lẹyin ni okeere. Awọn iṣisẹ meji wọǹyii jẹ eyi ti a gbọdọ ṣọra nipa rẹ̀. Bi a ti n kuna lati gbadura ati lati ka Ọrọ Ọlọrun – nini ibarẹ pẹlu Oluwa – ni afo ni n wà laaarin wa ati Olugbala, bi a ba si joko sinu iru ipo bayii, nikẹyin a o sẹ́ Ẹni naa ti O ra ọkàn wa pada.

Nigba ti idanwo dé ba Peteru oun kò ni agbára lati duro. Ọmọbinrin kan ti i ṣe iranṣẹ ni o sùn un ni ẹ̀sun pe ọmọ lẹyin Jesu ni oun i ṣe, o si sẹ́ kanlẹ. Eyi ni Peteru ti o ti funnu pe oun yoo kú nitori Jesu. Wo bi a ti jẹ alailagbara to ninu ipá ti ara wa! Lai pẹ awọn miiran tun tọka si Peteru, o si sẹ́ kanlẹ kedere pe oun ko mọ Jesu ri. Nikẹyin o binu gidigidi, o si bẹrẹ si i bura.

**Akukọ Kọ**

Lojiji, boya pẹlu iró ti o ju ti sisán àrá lọ leti Peteru, akukọ kọ. Ki ni ṣe ti eyi dẹruba a? Nitori Jesu ti kilọ fun un tẹlẹ pe ki akukọ ki o to kọ Peteru yoo sẹ́ Oun nigba mẹta. Jesu paapaa gbọ́ nigba ti akukọ kọ. O si fi oju ibanujẹ wo ọmọ-ẹyin Rẹ̀ onitara ṣugbọn ti o jẹ́ alailagbara. O maa ṣe o! Wo bi yoo ti jẹ́ ohun abamọ fun Peteru to! O wa mọ daju pe Oluwa jare gbogbo ẹ̀sun ti O fi oun sùn; o jade lọ, O si sun ẹkun kikoro.

Ṣugbọn ireti wa fun Peteru. O ronupiwada. Ki i ṣe titobi ẹ̀ṣẹ awọn ẹlẹṣẹ ni yoo sé ilẹkun Ọrun mọ́ wọn, bi ko ṣe kikọ̀ ti wọn kọ̀ lati ronupiwada. Peteru ronupiwada o si ni iyipada ọkàn ati leke gbogbo rẹ̀ o pada di Ọwọ̀n ninu ijọ, o si sọ awọn ọmọ-ẹyin iyoku di alagbara. Ni ọjọ́ Pẹntikọsti, lẹyin ti o ti gba agbara ifi Ẹmi Mimọ wọ ni, o ṣe iwaasu ti o ya ni lẹnu to bẹẹ ti ẹgbẹẹdogun eniyan (3,000), fi ri igbala ni ọjọ kan ṣoṣo. Lẹyin iṣẹ-iranṣẹ ọpọ ọdun ti o ṣe pẹlu otitọ ọkan, o kú iku ajẹriku nitori Kristi Ẹni ti o sẹ́ nigba kan ri.

**A Ké Akoko Iwadii Kuru**

Iwadii ọran ti n lọ bayii ninu ile Kaiafa, nigba ti o si di afẹmọjumọ wọn fi ohun ṣọkan lori idajọ pe Jesu jẹbi ikú. Gẹgẹ bi ilana ofin awọn Ju wọn gbọdọ ṣe iwadii iru ọran bayii fun ọjọ mẹta: a gbọdọ ṣe ipinnu idajọ ni ọjọ kin-in-ni: ọjọ keji wa fun titun ọran naa yẹwo, niwọn bi o ti le ṣe e ṣe awọn adajọ naa gbọdọ mu ọkàn wọn kuro ninu ọran ẹjọ naa; ni ọjọ kẹta wọn yoo si tun jumọ pade lati tun dibo lori ọran naa. Bi adajọ kan ba ti dibo pe "ko jẹbi" ni igba kin-in-ni, oun ko le yi ipinnu rẹ̀ pada mọ. Lọna bayii afo ṣi silẹ lati dá eniyan lare ki a si dá a silẹ. Ṣugbọn ọna ti a gba ṣe iwadii ẹjọ Jesu yatọ si eyi nì; laaarin wakati diẹ loru ni wọn sare ṣe gbogbo rẹ̀.

**Kò si Ẹṣẹ Kan Lọwọ Jesu**

Awọn Ju wa labẹ ijọba Romu, gbogbo ẹjọ ti o ba jẹ mọ idajọ iku ni a gbọdọ mu lọ sọdọ ijọba Romu fun iwadii. Nitori naa, ni kutukutu owurọ, awọn agbajọ eniyan-keniyan wọnyii mu Onde wọn lọ si gbọngan idajọ Pilatu. Lẹyin ti Pilatu ti bá Jesu sọrọ fun igba diẹ o wi pe, "Emi kò si ri ẹ̀ṣẹ lọwọ ọkunrin yi." Awọn Ju ko fẹ eyi. Wọn n fẹ ki Pilatu ti ipasẹ ọrọ wọn da A lẹbi iku, ani lai tilẹ gbọ́ ọrọ ni ẹnu Rẹ̀. Pilatu ko ha le gba ọrọ ẹnu wọn gbọ́ bi?

**Kristi Niwaju Hẹrọdu**

Nigba ti Pilatu gbọ́ pe lati Galili ni Jesu ti wá, o ro pe oun le yẹ ṣiṣe idajọ Rẹ̀ silẹ nipa riran An si Hẹrọdu, ẹni ti ijọba Romu fi jẹ baalẹ agbegbe ibẹ. Inu Hẹrọdu dùn lati ri Jesu nitori o ti gbọ́ nipa awọn iṣẹ-iyanu Rẹ̀, o si ni ireti pe oun yoo ri ki iṣẹ-ami diẹ ti ọwọ Rẹ̀ ṣe. Ṣugbọn Oluwa ki i ṣe iṣẹ iyanu lati tẹ́ ọkan eniyan lọrun. Ṣugbọn nigba ti Jesu dakẹ pẹ lai sọ ohunkohun si ọrọ ifisun ti o ti ẹnu Hẹrọdu jade, awọn ọmọ-ogun rẹ̀ fi i ṣẹsin, wọn wọ Ọ ni aṣọ daradara, lati fi hàn bi ẹni pe wọn n tẹriba fun Un. Hẹrọdu ko fẹ ṣe idajọ kankan rara, nitori naa a tun rán Jesu pada si ọdọ Pilatu.

**Jesu tabi Barabba?**

Lakoko yii iyawo Pilatu ti lá ala buburu kan, ẹru si n ba a ki Pilatu má ba lọ dá ẹjọ ikú fun Jesu, ki wahala nla má ba wa sori wọn. Ẹru ba Pilatu, bakan naa, o si ranti pe o jẹ́ àṣà lati maa dá onde kan ti i ṣe Ju silẹ ni ọdọọdun ni akoko Irekọja. Ẹni kan ti o ro pe o buru ju lọ ni o yàn, apaniyan ti o n mu ipaya ba awọn eniyan; o si fi siwaju awọn Ju lati yan arufin paraku yii tabi Jesu. O ro pe dajudaju wọn yoo yan Jesu, ṣugbọn wọn kigbe soke pe, "Ki iṣe ọkunrin yi, bikoṣe Barabba." Pilatu ro pe oun yoo ru ọkàn ibakẹdun wọn soke bi oun ba paṣẹ pe ki a na Jesu; ati pe oun yoo le da A silẹ nigba naa, ṣugbọn wọn tun kigbe soke pe, "Kàn a mọ agbelebu." (O lodi si ofin wọn pẹlu lati na eniyan ṣiwaju ki a to ṣe idajọ rẹ̀).

Pilatu ni idaniloju pe ẹni rere ni Jesu i ṣe, ṣugbọn oun ko ni ọkàn igboya lati duro ti ohun ti o mọ pe oittọ ni. O bẹru awọn eniyan. O duro niwaju wọn o si wẹ ọwọ rẹ̀ lati fi hàn pe oun ko ni ọwọ ninu ẹṣẹ buburu ti awọn eniyan wọnyii dá, ṣugbọn omi kò le wẹ ẹbi rẹ̀ kuro niwaju Ọlọrun.

**Ijiya Awọn Ju**

Awọn Ju wi pe, "Ki ẹjẹ rẹ̀ wà li ori wa, ati li ori awọn ọmọ wa." I ba ṣe pe wọn mọ ohun ti wọn n wi! Ko pẹ lẹyin ti Jesu kú, a pa Jerusalẹmu run, ijiya aini nla si de ba awọn Ju. Gẹgẹ bi akọsilẹ oniwe-itan ti a n pe ni Josephus, ọkẹ marundinlọgọta (1,100,000) ninu wọṅ ni a pa, awọn ti a si kó lẹru jẹ ọkẹ marun din ẹgbẹẹdogun (97,000). Ibẹẹrẹ ipọnju wọn sa ṣi ni eyi jẹ. Wọn ṣi n jiya sibẹ titi di ọjọ oni nitori wọn kuna lati gba Messia wọn nigba ti O wá, wọn si da A lẹbi lati kú iku ika ati ẹgan ti ori agbelebu. Nigba ti Jesu ba tun pada wa, awọn Ju yoo mọ Ọn, wọn o si maa ṣọfọ Rẹ̀ "ẹniti nwọn ti gún li ọ̀kọ" (Sekariah 12:10).

## AWỌN IBEERE

1 Ta ni fi Jesu hàn? Fun eelo?

2 Nibo ni awọn agbajọ eniyan-keniyan gbé ri Jesu? Akoko wo ni?

3 Ki ni ṣẹlẹ si awọn ọmọ-ẹyin Jesu nigba ti a mu Un gẹgẹ bi onde?

4 Njẹ a ṣe iwadii ẹjọ Jesu ni ọna ti o tọ́?

5 Ki ni ipinnu awọn onidajọ? Ki si ni idajọ?